COMPLIMENTARY COPY

**Akiyesi**

A nfẹ Ẹniti yio ma a wa ta Iwe Irohin Imọlẹ. Ni agbegbe Ilorin tabi Ilu miran. Ẹ kowe si ọdọ Ọgbẹni: R. O. Adedeji Esq: Ni P. O. Box 12. Ilọrin

# IROHIN IMOLE

MOTTO: IMOLẸ „DE," OKUNKUN PARADA.

**Notice**

HELLO! HELLO!!

For all your Electrical appliances &work Consult:-

Shegun Elect. Stores.

Stockist of Elect. Cables, Fittings an accessories. Workshop & Showroom 15 Jebba St. (East) Ebute Metta.

VOL. III No. 147 MONDAY MAY 9 — MAY 15 1960 KỌBỌ KAN (1d)

# Iya kan pa omo re ni ilu Oyinbo, won si ju si ewon

LEEDS, ENGLAND:- IROHIN KAN TẸ WA LETI LATI ILU LEEDS NI ILU OYINBO PE WỌN SE ẸJỌ APANIA FUN IYA KAN TI O PA OMO RẸ KAKA KI WỌN DAJỌ IKU FUN U NIṢE NI ILẸ ẸJỌ GIGA TI LEEDS JU SI ẸWỌN ỌDUN MẸTA.

Ohun ti o fa sababi, ati Irohin rẹ ti eti wa tẹ niyi. Iya-Afin (Mos) Margaret Atkinson ẹniti ile ẹjọ ko jẹ ki o sọrọ rara ju ọrọ ti o ti sọ fun awọn Ọlọpa lọ ni Obinrin na ti o fi ibọsẹ nailọnu fun ọmọ rẹ pa.

Gẹgẹbi ọrọ ti o sọ fun awọn Ọlopa ohun ti o ni o fa eleyi ni wipe Ọkọ on ti o jẹ Onisowo nyan ọkan ninu awọn ọmọbinrin ti o nbaa ṣiṣẹ ni ale. Orukọ ọmọbinrin na ni Paulineo' Reilly, ẹni ọdun mẹrindinlọgbọn. Obinrin abiyamọ ti o fun ọmọ rẹ pa yi ni ọkọ on lo fa sababi yi. ọkọ rẹ ni ile ẹjọ tun kọ fun pe ki o ma wa sọrọ tabi jẹri.

OFIN ANU

Ọmọ rẹ ti Obinrin yi pa ni Rosemary Atkinson Nigbati awọn Igbimọ pipari ọrọ (Jury) ti wọ Iyẹwu fun bi nkan bi iṣẹju mẹsan wọn ni nwọn gbe ọrọ na yẹwo, nwọn si ri i pe Iya-Afin Atkinson ko jẹbi pipa ọmọrẹ ni a mọmọ pa bikoṣepe ọkan rẹ daru ki ọ to di wipe o ṣe ẹṣẹ yi, nitorina wọn ni o jẹbi adanipa (Manslaughter).

Adajọ Ọgbẹni Cassels wa ṣe Idajọ rẹ o ni ki o lọ si ẹwọn ọdun Mẹta. O ni ki o ma ṣe lero pe iya ni ẹwọn ti on fẹ lọ bikoṣepe a fi i si ẹwọn fun anfani ara rẹ ni. Ofin anu ti Igbimọ Asofin Gẹẹsi ṣẹ-ṣẹ ṣe ni Ile Ẹjọ fi ṣe ẹjọ Obinrin yi.

Ọgbẹni Jack Donald aladugbo ẹbi Atkinson sọ tẹlẹ fun ile- ẹjọ pe ọmọ awọn Atkinson ti orukọ rẹ njẹ Susan Atkinson lo jẹ ki on mọ pe iru nkan bẹ ṣẹlẹ ni ile wọn O ni niṣe ni Susan wa kankun ile ti on, ti on si tẹle lọ si ile wọn ti on wa ri iya rẹ ti o fi ẹnu si efin ti o si tẹ aburo Susan si ori ibusun pẹlu ara rẹ, ti o si fi ibọsẹ fun Rosemary pa.

Ẹniti o tun jẹri ni ọmọbirin Ọlọpa kan Mary Clay, ti o ni Iya-Afin Atkinson sọ fun on pe "On yio fẹ pa Susan pẹlu' O ni funra on ni on ṣi efin silẹ ni ile pe ki awọn le ku ti on si fi ibọsẹ fun Rosemary fun awọn Ọlọpa ni wọn wa ka ni ile-ẹjọ, Ile-ẹjọ wa ṣe idajọ gẹgẹbi a ti kọ si okeyi.

# Odun meta

## Ha! eti re melo?



Eyi yi ni Ẹrọ Alata to dara ju gbogbo eyi ti wọn ti nlo tẹlẹ ri lọ, lẹhin ata lilọ, o tun le lọ Igbado ati Ọka-Baba, at Ẹwa-ere orisirisi

**£45 ni a nta** Pelu Ẹnjinni Pẹtrol tabi ati pẹlu Elẹtiriki Muto.

O WA NI ṢỌBU

**Akoshile Brothers**

5, Balogun Street West,
P. O. Box 599
Phone No. 24395. Lagos.

## MOGBAYI BABY MIXTURE

OLURANLOWỌ FUN AWỌN ABIYAMỌ

MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ ogun pataki ta ṣe ni Aṣepe fun Awọn ọmọde, ati nlo ogun yi fun ọpọlọpọ ọdun sẹhin pẹlu idanilojo fun Awọn iṣẹ ribiribi ti o ti nṣe. MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ egbogi to dara pupọ fun igbona ikọ, otutu Aipari, Osi inu ọmọde, jẹdi jẹdi Kokoro ori ọmọde. O dara fun ọmọde ti ko tete rin ati fun awọn aisan miran bẹbẹ lọ. O nmu ki ọmọde ma nsun fọnfọn, o nmu ki ehin hihu jẹ itọ run fun awọn ọmọde. osi njẹki awọn ọmọde tobi. osi nmu wọn dan ni awọ. Ẹnyin Abiyamọ, ẹku afojuba egbogi yi. Aran yin lati pa MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ egbogi ti kojẹ mani fun awọn ọmọde. Ijafara lewu pupọ, tete lọ ra ti ẹ gi ile itaja Egbogi towa ni Adugbo rẹ.





Igo kekere rẹ jẹ 2/6d Igo nla jẹ 4/6d

LILO RE- ibi kekere kan lemeta lojumo

*Wholesale Distributors*

A. K. KARIMU ANJOLA & BROTHERS

6, Balogun Street West Lagos Nigeria Phone 22515

34, Docemo Street Lagos Phone 264247

# IMOLE

ESIN ORO WA
IMOLE DE OKUNKUN PARADA
Editorial Works & Office
16, Bmgbose Street,
Lagos
Telephone.- 21985
United Kingdom Representative
Publishing Distributing
177, Regent Street.


## Nipa ona oko gbokegbodo wa

Awa Iwe Irohin Imole fe ki Ijoba Apapo mo wipe Ominira ko gbodo de bawa pelu rederede ti awon oko wiwo loke-lodo ti a ni nse lowo bayi.

RELUWE

O ye ki Ijoba Apapo ti o wa fun gboke-gbodo oko Ogbeni R. A. Njoku ba awon igbimo Reluwe soro, nipa pe o ye ki won wa tun oko Reluwe se, papa ti ipo keta. Eniti o ba ti wo oko Reluwe ri lo si ajo tio jin ni ohun ti a nwi yi yio ye daradara, loto ipo kini ati ekeji dara, sugbon ipo keta ko se fi oju ri rara, idoti eri ati orun, ki i je ki enia ti o ba wo oko Reluwe ipo keta gbadun rara.

O dabi eni wipe awon alase Reluwe ko bikita rara fun ipo keta ti oko won eleyi ke re, ko je ohun ti o to. Ohun kan ke ti a fe ki alase Ijoba Apapo ti o wa fun gboke gbodo oko tun ye wo ni pe oko Reluwe ko yara rara, o nto wakati merin tabi marun nigba imiran ki oko Reluwe ti o fi Eko sile to le de Ibadan eleyi ko mu ni lori ya rara moto ti o gba ona kana ti Reluwe gba nlo wakati meji abo kilo wa fa ti Reluwe? opolopo awon alejo tao gba nigba Ominira ni yio fe ba awon ilu orile-ede wa wo, ona ti o ya ti owo re si je poku niwon yio le gba, ode ye ki won le gbadun irin ajo won ni ilu wa ki won ba mo pe loto Naijiria ti de.

MOTO ATI BOSI

Ti Bosi lo ye ki a koko so awon agbowo ninu bosi gbodo ko iwa pele, o de ye ki won mo pe eniti o wo bosi ki i se alakori, nitortua o ye ki won mo ati ma bowo fun awon ero won.

A dupe lowo awon alase bosi pe asiko ti bosi fi ndu-ro ko pe bi ti atijo mo ele-yi je ohun iwuri.

Ti awon oni moto ke, oye ki awon omo bolekaja a lo ko iwa pele, iwa ole-won ati aladikita ti won nhu nisinyi ko bo si rara.

OKO OJU OMI

O ye ki awon alase ports Authority, tun awon oko ti o nlo lati Eko si Apapa se, tabi ke ki won wa kun awon oko na, iseju medogun ti awon oko na nrin lati Eko si Apapa ko je ohun ti o dara rara, o ti yo ju, gbo-gbo wa la de mo pe Apapa ki ise orun, o ye ki oko kati-lini le ma lo bi iseju marun lo si Apapa, iseju marun bo.

Apapo alo abo ko gbodo ju iseju medogun lo, dipo abo wakati ti o nlo nisinyi lo.

Awon oko ports ti o nlo si idale ke re e ko to, o ye ki won fi kun. A le so pe Alase Ijoba apapo ti o wa fun igbokegbodo oko yio ri si eleyi.

OKO OFURUFU.

A ko le ri ohun kankan so si ti awon oloko ofurufu ju wipe owo oko na ti won ju, o ye ki won din ku, ki opolopo enia ba le ma wo o.

Ni ipari, a lero pe Ogbeni R.A. Njoku Alase Ijoba fun igbokegbodo oko yio ri si awon oro ti a so wonyi, yio ye won wo, yio si se dede.

## Ina Eletiriki pa enia merin ni Mushin

Enmo nla sele ni Mushin ni kutu o wuro ojo aje (Monday) ti ose tokoja ni gbati iya agba kan pelu awon omo omo re meji ati odomobirin kan ti o nto omo lowo ko agbako okun (wire) ina eletiriki ti o si pa won dorun.

Ohun ti o fa idi iku awon eni merin wonyi ni iji ti o fe ni oro kutu ojo aje (Mon-day) ti o si gbe orule ati ipele kini pelesi kan ni 7 Adedoja Street ni Mushin lule, iji na si wa ja okun ina (wire ti adugbo na ni pataki ti ile ti o wo lule.

Eniti o ko ko iku tire ni Falilatu Adunni Ajani eni odun marun-din-lo-gbon, eke lo fe lo se k. o to lo ki esi bo okun ina eletiriki oko re so fun ... pe ki o ma jade lo woran, sugbon o ko jale

O tile fe gbe omo re lo ki oko re to gba omo sile lowo re esekese ti o ti ti kese sinu okun (wire) ina ni o ku.

ETI RE MELO

Iwe Adura awon KERU-BU ati SERAFU ti o sese jade, eyiti o je lilo fun awon Woli Aladura nikan-soso lasiko kan ri, di tita fun gbogbo gbo. Ko si elegbe re. Sile marun abo (5/6d) pere. A le ri ra ni 36, King George Avenue Yaba.

MO JUBA AIYE

A nta nkan orisirisi to je mo ohun elo Ogboni ati oguniogo ohun miran to le se omo Araiye ni anfani nigbesi ile Aiye won. Itagbe, Opaga, Ege, Aso Ibora-Aiye, Ileke Iyun, ETC.

Kowe fun Iwe Itaja ki-kun pelu 3d Stamp si:- Apena Iledi Abalaiye, 26, Owodunni Street, Palmgrove Ikorodu Road Yaba Nigeria.

## Eni ti o nya aworan fun Isoso arin ilu Eko fun OMINIRA



Aworan ti e nwo loke yi ni ti Ogbeni Beverley Pick, eniti okiki kan kakiri agbaiye gegebi yaworan-yaworan Ogbeni Pick ni o nya aworan ti a o fi ko se oso kakiri Eko fun ajoyo Ominira Naijira. Ogbeni Pick ni o ya aworan re ni ile-ise re ni Londonu nibiti o gbe awon aworan ti o ti ya fun isoso ni titi Eko.

